# ENMQ PELEMBE ENGLAND LADY DI AJQMQGBE

### Ikede

Awa ikede yi f u a gbogbo ẹnyin Okowo wa ati asoju wa wipe, ẹni keni ti owo ba seku si owo re ki o tete fi ranse ni-tori gbogbo ohun elo ti a fi ntẹwe irohin lo ti gbe owo leri.

Enikeni ti ko ba fi tire ranse ko da iwe re duro ao si sa agbara lati gba owo wa n owo re. Olota

**ELETI OFE**

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

### Just Arrived

Standard Cookers the newest Scientific Invention without wick, pump and injection no electricity required

Call at Sylves & Company 4 Onikepo Street Lagos,

near Corona Cinema, come and buy to avoid regrets.

VoL VII No. 412 LAGOS (SATURDAY) ỌJỌ ABAMETA APRIL 23 1955, IYE OWO ELETI ỌFE KỌBỌ MEJI.

## Ijoba Yio Wadi Igbimo NCNC Nilu Ibadan.

**Ibadan** Ijoba Iwo Orun ile Nigeria yio yan enia kan ni oluwadi lati se ofin toto iwadi igbimo N.C. N.C. ni ilu Ibadan, nipa ise ti a yan fun won bi nwon se e tabi nwon fi nse arede. Ogbeni Rotimi Williams ni yio yan oluwadi na. Sugbon a ko yiti mo eniti yio yan na. Iwe miran yio tun jade ni-gbati a ba yan Oluwadi ni-gbana, a o so akoko ti iwadi na yio bere, sugbon gegebi a i li ero, iwadi na yio bosi inu osu May.

Latigba ti a ti da igbimo N.C.N.C. Ibadan sile ni odun 1954, o fere je wipe li ojoju-mo ni a ngbo irohin li okan-ko-jokan nipa iru iwa ti igbimo yi hu. Esun ti a gbo nipa igbimo na ni wipe nwon ko sise won li eto, nwon ko si tele ilana ofin ti ijoba se sile.

Pataki ohun ti ijoba nfe se iwadi le lori ni wipe yala awon esun ti a daruko nwonyi je iwa igbimo N.C. N.C. nitoto tabi nwon puro mo won ni. Nitorina ki olukuluku wa so ti enu re.

## Passing Out Parade And Presentation Of Batons Of Honour

**MR J. A. MACDONALD**

By

ACTING DEPUTY INSPECTOR-GENERAL OF POLICE

A Passing Out Parade will be held at 5.30. p.m. on Wednesday, April 27, at the Southern Police College, Ikeja, when Mr J.A. MACDONALD, Acting Deputy Inspector-General of Police, will present Batons of Honour to members of the Police Force.

The Band and Drums of the Nigeria Police will beat "Retreat." All Friends of the Force are Cordially invited to attend. Spectators are asked to be in their seats by 5. 15 p.m.

**R. H. V. BILES**

FORCE STAFF OFFICER




## ENMQ PELENBE England Lady Di Ajomogbe

Irohin kan to ta si wa leti ni wipe omobinrin kan to lo si ilu Oyinbo ni asiko kan ti gbogbo enia ro wipe ise rere kan lo loko l'ohun, asamosamo ise aj'omogbe ni jagun lo ko nilu Oyinbo. Eyiti a gbo ni wipe England Lady yi fi aiko loyun bimo-eyi ara.

Egbo bi oro na ti lo:- Omobinrin kekere kan lo lo loyun apete, ni olutoju re yi ba mu yera si ehin-odi, ni-toripe ki okiki re ma ba kan pupo larin ilu ki ami fa oro yi gun lo titi mo, omo to l'oyun bimo ki a wi, ki a fo, iya ti ko loyun lo si pada di iya ikoko tape nipa iwa ay'nike, omo to bimo ko tun je iya ikoko mo, sugbon nigbati awon agbalagba fi ogbon inu wo o, nwon ri wipe ayinike lo so iya ti ko loyun di abiya-mo, awon na yio si lo iwa ayinipada lati fi gba omo fun olomo.

Bayi ni [illegible] Lady fun iya to bi omo re ni oro badi "Oloruka gb'oruka owo oga dofo"

## Western Nigeria Radio Magazine

QJQ TI AO DA SILE NI QJQ MONDAY, APRIL 25th

NI AGOGO MEJQ ABQ ASALE

Lojo yi ni iwo yio gbo ohun Qlola Sir John Rankine, ti o nse Gomina apa Iwo Orun ati Oloye, Obafemi Awolowo ti o nse asiwaju awon Minister apa Iwo Orun. Ati Alaiyeluwa Sir Adesoji Aderemi kini, Qba Qni Ile Ife ati Qba Akesua keji Qba Ibini.

Eniti yio tun soro ni Qlola Anthony Enahoro on ni yio soro nipa ohun ti a da sile yi.

Lehin eyi, ao tun gbo ohun orin ni ede ibile lati inu Afin Qba Ibini ati lati inu Afin Qni Ile Ife.

Iwo ko ni fe ki a fi nkan wonyi se irohin fun o.

## Today's Sport

SCOA I will meet Railway I on the King George V Stadium to day in the Division I league match.

The two teams were only known at the end of last season, SCOA may steal the show from their more powerful opponent if the former show sign of weakness

# ELETI QFE

A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJQ

EDITORIAL OFFICE & WORKS
28 Kosoko Street, Lagos
P. O. Box 467

CABLES & TELEGRAMS
"ETI-QFE LAGOS"
Phone 23370

VOL. VII NO. 412 LAGOS SATURDAY APRIL 23 1955


## "Iwo Ko Gbodo Pania"

### Beli Oluwa Wi

Iwa ipania ni ipa oro se ngbile larin ilu Eko yi nisisiyi, beni ko si ohun meji to fa iwa buburu yi to ju wipe awon enia ti ko ni itiju ti ko si emi rere kan l' okan won, awon ti nwon nfe la ola ojo laiko sise, ti nwon ko si ko lati gb'emi elegbe won lati le ri aye ko ohunolohun fise ti ara won.

Ko tun si wipe enikan pelu enikeji re ja ni o sesi jasi iku mo ni ode Eko wa isisiyi, afi ki awon janduku enia wonyi lo ko arawon jo fi ero se okan le eniti nwon fe pa l'ori, vala nitori ati le ri aye ko eru re ni tabi lati se ise Olosa lati fo Sobu onisobu ki nwon le ri aye ko eru iyebiye lati le ola ojo, eyiti nwon o fi pa eda elegbe won l'ekun.

Bi awon Alufa ijo Sosi ti nse waasu lori iwa buburu yi, beni awon Alufa Musulumi ko kere lati ma se wasi fun awa omo Anobi Adamo wipe gbogbo ese l'oni idariji sugbon eniti eni omo enia bati owo re bo,, ko si idariji fun u niwaju Olorun.

Sibesibe, awon enia aiye, paapa nilu Eko ti a pe ni Olu ilu Nigeria ni irufe iwa ipania ni ipa oro bayi tun npeleke si. Ti, Alufa Bisiriyu Apalara lari ti a nwi, awon jagun ebele enia alailanu na tun solu Gbadamosi Olorunnisola, Aso sobu S.C.O.A, ni idumagbo, eyiti a o tun gbo niti Ogbeni Akorin kan ti oruko re nje Isreal Njemanze ni ona Mushin niwaju oke Ebute Metta rogbodiyan ejo ti yen ni awon olopa oba mbe l'enu re nisisiyi.

Asiko na to nisisiyi fun Musulumi, Onigbagbo ati awon aboriso lati tewo adura si Olodumare Oba Oga Ogo, pe ki o jowo ba wa le emi esu jinna si awon enia olokan buruku wonyi, ti ati gbemi eda elegbe won ko je nkankan l'oju won, ki a le fi ifayabale gba ominira le wa ti a ngb'orun re lowolowo yi.


# JUST ARRIVED

## ORISIRISI IWE ADURA

Koran Esu Meji, Koran Esu Marun, orisirisi iwe Arabic fun adura ni asiko Awe ati nigba gbogbo ti a ba fe se adura ti o le mu enia ni ilosiwaju nipa Esin, ati nipa Owo tabi ki enia le ni ilosiwaju ni gbogbo aye.

Orisirisi aworan awon Anobi wa fun tita.

Wa ra tire lodo:—

ALHAJI OPELOYERU

37, Itolo Street
LAGOS.


# Polowo Qja Re Sinu Iwe Irohin Eleti Qfe





## Awure Bamwo

Qmọ t'a fi Bamwo fọ ki gbo' oa, ọmọ t'o mu Bamwo ki ẹ'o' kunrun, ẹakaṣaka l'ara wọn ni

Bi nwọn ba s'eropa lọsan, nwọn a sun fonfon l'oru. Awọn l'owere ji t'on s'ẹrọ, ndaji jeun bi ẹmọ. On li a da l'abeyamọ bendere pa ki o robọ abiku ki o ma wa Bamwo, ra kiri,

Njẹ iko ṣi Bamwo mọ ṣinimọ-ṣinimọ. Azun ṣi Bamwo mọ ṣinimọ-ṣinimọ" Wa ra Bamwo fun ọmọ rẹ lọdọ wa. Igo kekere 2/6d. Igo nla 4/- Owo ẹkọ 1/6d. fun igo kan.

## The Egba Trading Aradan Stores

18, Denton Bridge St. P. O. Box 2, Ebute Mẹtta.


## Qro Qrunmila Bara Agbonmiregun

# Qna Meji Pataki Ni Oruko Qrumila Pinsi

### LATI QWQ ESQ IKOYI

Li ọna meji pataki ni awọn Babalawo mọ oriki Ọrunmila si, Ekini. A nwipe Ọrumila ko se, iyẹn ni wipe, ko dani lohun nitoripe aiwọn bi On fura rẹ ti jẹ ẹni aimọ fun ni. bakanna li o jẹ eni aiṣe fun ni pelu Awọn Babalawo rope bi o ba ṣe wipe awọn lẹ ridi ori iwa Ọrum.la ni ariyika, iba ma ṣe fun wọn iyọn ni wipe, nigbakigba ti nwọn ba ti pee yio ma da wọn lohun.

Ekeji. Ifa sọrọ ni kiko jọjọ tobẹ ti ko si ẹniti o le kọ akopari rẹ gbogbo ọna ti a ngba lati fi dibe jo itose ọrọ tabi iwadi ọrọ li enu Ọrumila, Isọrọ ti o mbẹ ninu Ifa kiko niyi. Ọtalugba din merin ni gbogbo ọdu ti o wa (256) merindilogun pere ni ibo didi (16) laika ọna kọna ti nwọn le jasi tibi, tire.

Ki enia to le di Babalawo ti o gbọ Ifa rere o ni lati mọ gbogbo awọn Odu Ifa nwọnyi ati Ibo rẹ. Iyẹn ni wipe ki a to le pe enia ni Babalawo tabi Awiyẹ tabi Araba, Oluwa rẹ ni lati mọ odu merindilogorun le-iọgbaji ati awọn ẹbọ ti a ni lati yaan nitori alle ko Ifa Pari yi li o nmu awọn Awo miran lati ranṣẹ pe Awo ti o mbẹ ni tosi lati wa ba on yẹ Ifa yi wo, nitoripe ẹni o mọ eyi ko mọ eyi. Nigbati Babalawo kan ba ẹl odu Ifa kan ki, tabi o ṣi ese Ifa kan, kiakia ni lo yan ẹbọ funtu re, yio si fi Ibo didi bere, beni tabi bẹkọ- Bi Ifa ba kọ Ibo na, nigba na no mọ wipe a kotti kan ese Ifa ti a nfe sọgbọn, bi Ifa ba gba, a je pe eyiti a yan nani,

Awọn Babalawo iba pe ogoji. ẹtẹ Ifa ti ẹniti Ifa gba Ibo tirẹ ni a o ru ni ẹbọ. Ṣugbọn eiṣe ati aiṣe rẹ wa ku si ọwọ Ọrunmila, eyiyi ni a npe ni Aiya Afọṣẹ larin awọn Babalawo.

Ki o to di wipe Babalawo kan ni Awiẹẹ tabi Aiya Afọṣẹ li enu, o ni lati kọ akopari gbogbo Odu Ifa ni gbogbo ọna rẹ, tibi tire ti o ma mba ẹda lorilẹ aiye. O ni lati kọ gbogbo ẹbọ ti a nyan, fun Odu kọkan; ko gbọdọ ninu meji si Ọrunmila, nipa ṣiṣe bayi, ni Ọrunmila yio ma gba ẹbọ rẹ nigba gbogbo.

Bi ifa kan ko ba ṣẹ, bi a ba si wadi rẹ wo, a o ri gbangba pe aiṣe ko nṣe owọ Ọrunmila, bikoṣe lati ọwọ Babalawo ti ko pe ninu iwa rẹ si Orunmila. Ijinlẹ ti o mbẹ lokan awọn Awo ni wipe a ko gbọdọ yẹ Ọrunmila kuro nipa rẹ, ki aiye maṣe bajẹ. Nitori eyi ni awọn Babalawo ṣe nki Ọrunmila ni Ọlọwa Aiyẹrẹ.

## Ọja Ejinrin Ti Di Erebe

**Ejinrin** Awọn Olotu ijọba ibilẹ Ọja Ejinrin ti se eto titun si ọja Ejinrin ni ire eto ti yio mu irọrun wa fun awọn ara ti o nwa na ọja na.

Ara eto titun ti awọn se ni wipe awọn Alata, yio wa ni isọwọ kanna Elẹja yio wa ni isọwọ kanna bẹni awọn Alaso, Onirun-wosi, Onigari ati awọn be-bẹ.

Enikeni ti o ba nfe gba isọ titun yio lọ sọdọ Akọwe ọja yio fi nọmba ti awọn fun ninu isọ atijọ j a d e Akọwe na yio gba lehin ti o ba ti san owo fun Akọwe yio t u n fun ni nọmba ti isọ titun nibiti yio ma se ọja.

Awọn ti o je eto titun yi ni Ajele Ejinrin kekere ti o ngbe Ẹpe ati awọn igbimọ ilu na pelu awọn aleyanlowọ wọn.

## Ọba Kan Ko Ku, Ọba Miran Ko Je

**Abraka** Awọn igbimọ, ijọba ibile Warri se ipade kan laipe yi nigbati awọn ara ilu Abraka kan daba lati je oye Olọta ilu Abraka miran dipo eyiti o wa nibe nisisiyi.

A ko le se Osegbe ki Onile ma mọ ko si ohun ti nwọn le da se nilu Abraka laido iwaju igbimọ ilu Warri.

Awọn igbimọ ilu Warri se ipade Ọgbeni P.I. Arawere lo gbe ọrọ na siwaju igbimọ wipe Agbada ko gbona agbado ke ta. Ọba kan ko ku Ọba kan ko je Oloye Ọgbeni D.O. Oafe ni ijọba ibile gba ni Olọta ilu Abraka gbogbo awọn igbimọ fi ara mọ nwọn si gba be Olọta yi ni yio ma lọ se asoju ilu Abraka ninu igbimọ ijọba-ipba ni Ibadan.

## Enia Gbe Ọdun Mejidilogbon Nile Ilarun Eyi Ara

**Portharcourt** Ọkunrin kan ti ara re ko le ti awọn enia re gbe lo sile alarun ni ile yi niwọ ọdun 1927 lati gba na wa, okunrin na ko san beni ko dẹkun lati ma ẹgbogi o je jije o ma mimu nwon gun ni abe. re awon lan li abe nwon ni tun ran pada.

Kini igbebin re? asehinwa asehinbo iku li opin ohun gbogbo- Beni okunrin na ku lehin odun mejidilogbon ti o ti gba bedi nile alaisan,

## Iro Li A Ngbo Oju Ko To Alafin

**Ọyọ Igboho** Nigba lailai ogunlọgọ ninu awọn gbajumọ ati ọmọ ti a bi nilu Ọyọ ni ko fi oju ri Baba Alafin ri Papas nigba a i y e Alafin Ladigbola.

Nigbani bi a ba wi fun eni kan wipe iku baba yeye ape o a rọrun fun Oluwa re lati lọ. Pokunso ju ki o lo fi oju kan Alafin Ladigbolu.

Igbati aiye oba Ladigbolu fọd° Ọyọ fere lati AreỌna-Kakanfo mu. Bi awọn Oloro Elegungun, tabi awọn Aberiaa be nwure lode Ọyọ nwọn o ma wipe ki Olorun mase jeki nwon riane pade Alafin.

## Ọpọlọpọ Ni Ọmọ To Fi Oruko Sile Fun Ilewe Ofe Nilu Abeokuta

**Abeokuta** Irohin ko to Afeju b a n i t i awọn omode were ti a sese fi oruko won sile fun ilewe Ọfofe ! ọdun yi ni ilu Abeokuta.

Nigbati a siro iye awọn ọmọde na nwọn je egba-mejọdinlọdun-run se siro wọn niyi:-

Ni agbegbe ile Ẹgba, iye awon ọmọ kunrin to foruko sile j e Ẹgbeta-din-ni irinwo l o ogota Awọn obinrin ni je egbeta din logberin o le mefa.

Ṣugbọn ni agbegbe ti Ẹgbado awọn ọmọkunrin to foruko sile je egba-lo-ledegberin ati mọkandiladọrun awọn obinrin si je egba-le ladoje o le meji.

## Ọlọpa Mba Enia Merinla Rojo Apania

**Yaba** Oku okunrin soja kan ti a ti ge si wewe ni nwon lo ba loju irin oko reluwe nigbati awon o l o p a debe nwon fura wipe ko daju wipe Relawe li o ge si wewe be. Nwon fi imufinle nwon ri ipaeje nile nwon si to ipa ejo na titi lo de Mushin. Ọpọlọpọ ni awon olopa ranse pe lati wa so ti enu w o n . Lehin ti nwon se iwadi t a n ni nwon le mu a w o n enia nwon yi ti nwon si fi w o n sun esun Apania.

Iwonyi ni oruko enia na ti olopa mbarojo iku ologbe Njemanze. Samuel Jegede. Yusufu Balogun, Peter Uwangwu, Michael Adeyemo, Amos, Shock Kayode, Sittn Bada, Ramonu Akanbi, Lawal Dada Cyril Anikwe, Dada Owolabi, Robinson Ototo, Laleye Adewale, Lamidi Ayinde, Kwase Gerald.

Lojo Monday 25th April ni adajo yio bere si gbo gegebi idi oro na ti lo. Gegebi oku okunrin n a t i j e o k u soja, awon soja li o lo sinku re pelu eto ati eye.


# AWO IKỌRIN (RECORD) TI DECCA



yio mu awon orin ti o fe ati awon akorin wa sinu ile re

Lo ra won ni sobu

**S. C. O. A.**

A ti da Eka titun kan sile ti yio tete ma fi awon eru ti o se pataki ranse

**S. C. O. A.**

Head Office: 40, Marina Lagos

Show Room Martins/Broad street Lagos

ati ni

Ibadan, Sapele, Warri, Onitsha, Calabar, Aba, Port/Hercourt, Kano, Enugu, Zaria, & Sokoto

# Irohin Lati Ilu Okere

## Ogun mbo diedie, ijafara lewu

**U.S.A.** Ogagun fun oko ogun ti ara ile Amerika kan ti o sese pada dele lati apa ile awon Rosia ati Saina ti rohin bayi fun awon Onise Irohin ile Amerika wipe.

Oba mewa, igba mewa. Ogbeni Charchill ti siwo ojan ise isclu, Ogbeni Eden si ti gbe owo ija wo. Nitorina ogun eketa si yio kari aye tun mbo, ijafara lewu.

Ogagun na rohin wipe laipe Ogbeni Mao - setong ti o nse olori awon arafin ile Saina, yio kolu egbe ogun Siana Kosek ki ogun nla yio si bere.

Nitoripe Mao - setong ni aimoye egbe omo ogun lodo 600, 000, 000. Sugbon babanna ni Sianke-Sok tun ni omo ogun tire, o si tun ni awon Rosia ni alatilehin.

Ibiti a gbo wipe awon fe fi se ibudogun ni siekuse kan ti a npe ni Maisu nile Saina.

## Egbe Young Mus im Se Ayeye

**Ilesha** Awon omo egbe Young Muslim Association ti ti igboro ilu Ilesha je awoye ayo kan fun Baba egbe won, eniti a npe ni Ogbeni Balogun ti o ti nse ajoju fun Oyinbo U.A.C. ati G.B.O. ni ilu Ilesha lati igba ojoj ojo wa.

Ese awon omo Eko ti o mbo ni Osogbo, Ife, ati Ilokun lo pe sibe, awon enia to wa nibe fere to odunrun ea'a.

## Ere Esin Sise Yio Bere Ni Ilorin Lipe

**Ilorin** Awon egbe Race Club ti Ilorin ti gba ile lati odo Oba Ilorin lati fi se gbalasa odan nibiti ao ma fi awon esin sure ije gegebi ti Eko, Ibadan, Kaduna ati Jos.

Malam Oloruko Oba ti Agbaji, ti enia a yan lati ma bojuto ilesewaju ibi-isare esin na. Oba Ilorin ni awon egbe elere esin na yan ni Baba egbe.

Awon enia nwonyi Alhadji ile Olowo, Alhadji Mustafa Olodo, ati Aminu Sango ni yio ma se alabojuto.

Berclays Bank ni awon fi owo pamo si, awon enia ti yio ma fi owo si iwe owo ki a to gba ni, Malam Nosiru Oniyangi, Ogbeni J. A. Ari-egbe, ati J. O. Odewusi a ti ero wipe ao ko ibi isare esin na pari laipe.

A se ope fun Salimonu Balogun Gambari, Bedeoria Oni-Tinko, Yisa Eiyiu, Alufa Amori, Yaya Kanike, ati gbogbo awon igbimo elere esin yi. Olorun ko rae yio logwo.

## Mosalasi Nla Oke Odo Fi Enia Joye

**Ebutemeta** Mosalasi nla ti awon Jeamo Musulumi fi awon enia nwonyi je oye. Nwon fi Lemomu Yusufu omo Oba joye olori awon Lemomu Ratibi ti Ebutemeta Abudu Raimi Erewemi joye otun Basorun Lemomu Gbadamosi Agoro je otun Olori Ratibi, Lemomu Tawakalitu je oye Olori Omokewu. Lemomu Yusufu joye otun Olori omokewu.

D'e alnu awon enia pataki ti o wa nibe ni Ogbeni M. M. Savage, Y. P. O. Sodeinde, Alufa M. K. Ekemode, A. K. Muhamed, L. Alabi, A. Ogunbambi, J. Odejayi Bakare Sogunro, T. Daranijo, Iyaafin Awaudu Aduke, Iyafin Sienra, S. A. Areago, A. K. Nofiya, A. Braimo, S. Akanni, R. Odejayi, Otenolape, ati Y. O. Ilori.

# Eto Fun Awon Alhadji

A se eda iwe yi lati inu iwe ijoba Sudan nipa awon eto ti nwon se fun awon ero Meka fun anfani awon Alhadji.

ASE TI A FE LATI ODO DOKITA.

Alhadji ti o ba nlo si Meka, ni lati gba iwe ase lati odo Dokita wipe, o ti gun abere, o si ti bupa. Apa-bibu nitori ki arun Sopona mase kolu eni. Lehin ti a ba ti bupa na tan, a ni lati jeki ose meji koja ki a to bere irin ajo. Bi a ba si ti bupa ti pe, ko gbodo tayo odun merin ki a to tun bu omiran.

A ni lati gun abere nitori arun Iba Ponju-ponju, ki ojo mewa koja ki a to bere irin ajo ko gbodo tayo odun merin ki a to tun bu omiran.

NIPA OWO

Gbogbo awon ajeji ti o ba nwo ile Sudan ni a fe ki o fi ye wa wipe nwon ti sanwo ijoba Sudan ati ti Ijoba Saudi ni asansile ati wipe nwon ni owo lowo lati san ni Sawakin (iye re je £E.10 lati Geneina) tabi beko nwon ni owo ni Banki ti nwon le fi sanwo yi.

Bi awon ero ba di owo dani fun inawo nwonyi Ijoba Sudan yio gba owo na pamo lowo re ni Geneina, nwon o si fun ni iwe eri yio si gba owo na pada bi o ba de Sawakin.

| Agbalagba | Omode | Omo owo |
|---|---|---|
| £E. 27-550 | £E. 13.775 | ko si owo |


## Imoran Fun Eyin Abiyamo

Oyin Abiye... 'Omorela' O dara pupo fun awon omode

A ma je ki omode ni oran sun dardara, o dara fun otutu, Iko ati orisirisi arun miran ti o ma nba omode ja ni asiko ebin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe o dara pupo fun awon omode.

**Omorela Baby Mixture**

SILE MEJI ABO (2/6d) FUN IGO KAN

o wa lodo

**Commercial Medicine Stor...**

QUALIFIED CHEMIST
10, Victoria Street LAGOS.



# Medical Department Western Region

## VACANCY FOR ESTABLISHMENT OFFICER

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment to the post of Establishment Officer in the Medical Department, Western Region.

SALARY SCALE— A1, £570-40-£1,290 per annum.

QUALIFICATIONS: Candidates should be not more than 45 years of age and posses considerable administrative ability and have wide experience of office organisation.

DUTIES: The officer will be required to undertake the following duties:

(a) Dealing with all staff matters, such as promotions, engagements leave, disciplinary action, etc.

(b) Secretaryship of the Departmental Selection Board and Promotion Committee, Consultative Committee, Union Negotiating Committees, and Tenders Board.

(c) Advising the Director with regard to staff policy, organisation, salaries and wages.

(d) Preparation of Government Indents for supplies and staff Indents for submission to Crown Agents.

(e) Such other duties as the Director may assign to him.

OTHER CONDITIONS OF SERVICE:

(i) The post is pensionable and in the case of a new entrant in the Government Service appointment will be on probation for three years.

(ii) An outfit allowance of £60 is payable on first appointment.

(iii) Rent is payable at the rate of 10 per cent of salary when an officer is occupying Government quarters.

METHOD OF APPLICATION:

Applications should be adressed to the Secretary, Western Regional Public Service Commision so as to reach him not later than 30th April 1955.

Applications from candidates in Government Service should be submitted through the Head of the applicants department and be accompanied by a confidential Report.

## Patapata Akuko Ko Tayo Odun Meta

Olotu,

Gba mi laye lati se alaye yi fun gbogbo awon omo egbe Alakuko bayi wipe, Asebi Adame (Adam) lo gero fun igi ope pe, lehin-leh n ni gran Olube aso, so ni si igi ti yio lowa, ti yio si siyi si ojo eri re yio to ti igi ope. Gbogbo eniti o ba rirun ri igi Ope tabi o lala si igi Ope tabi ewe tabi igi, tabi eso re lasgun ala ti o je fun eniti o lala na.

Sugbon Akuko bi o ti wu ki o pe laiye to, ko le tayo odun mete. Bi enia ba si lala ri eiye Akuko li ojuran awon o je kete si eniti o lala na.

Nitorina Egbe Olowo ni egbe Awolowo Moto ni yio pa akuko su, su.

Emi ni,

Y.A. Komolafe.

Ara Jos.

## Idahun Si Ibere Gbadamosi Nipa Eta-oko

Olotu,

Iwe Iroh'n yi ti se idahun si ibere oruko awon omo ti a bi ni meta wipe Oni, Ula ati Otunla ni nwon. Awa paapa si fi ara mo be a ioripe nigba papo ni a ma ngbo iru oruko bawonyi.

Sugbon Ogbeni Kelebu Ogungbile nfi ye wa wipe o r u k o ti awon ope awon omo ti a bi ni meta ni Taiwo, Kehinde, ati Alaba

Mo fe lati fi ye Ogbeni Ogungbile wipe rara oro na ko je be. Alaye re ni ngo se yi bi a ba bi no ibeji ao pe akobi ni Taiwo, ao pe ekeji ni Kehinde, Omo ti iya ibeji ba tun bi tele awon ibeji ni a npe ni Idowu, Omo ti obinrin na ba tun bi tele Idowu ni a npe ni Alaba omo ti iya na ba tun bi tele Alaba ni awon ape ni Idogbe. Bi oro na ti je niyen.

Emi ni

Imam Adeen.


# Egbogi Ti Colgate Ti A Fi Nfo

# Ehin Nikansoso Lo Daju Ti O Si

# Nmu Ireti Wa Fun Qpo Enia

### LQSAN, ATI ORU, KO NJEKI EHIN ENIA BAJE

Lilo ti opo enia nlo egbogi yi fihan wipe egbogi yi ko njeki ehin enia baje pelu egbogi Gardol. AwonAlase isegun ehin ti se ayewo re fun odun kan pe egbogi na ko nkuro beni ki nsa. Bi o ba sa ti nlo ni ojojumo, laro ati ni ale, ko ni jeki ehin baje t'osan t'oru.



Sodium N-Lauroyl Sarcosinate

SAME FAMILIAR PACKAGE



**OKAN NINU AWON OJOGBON ONISEGUN EHIN TI SE AYEWO ORO YI.**

A ti fi Ododo oro yi han ninu iwe ti awon Onisegun ehin te, nwon si ti gba wipe egbogi ehin ti Colgate pelu Gardol je eyiti o dara fun ehin to baje ju egbogi miran lo. Ntoripe egbogi Gardol ki njeki ehin baje, lo se jeki awon alase gba wipe egbogi Colgate ati Gardol lo dara julo.




Ko si egbogi ehin kan ti o dara bi eyi.
Ko ni jeki enu re run
Ko si ni jeki ehin re baje

# O Dara Tosan Toru Ko Njeki

# Ehin Eni Baje

**Kere o!**

A ti ni orisirisi o g u n Germany to sese de, fun onirunru aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tire ko to tan.

J. A. AJAO BROTHERS
Medicine Store

7, Egerton Road, Lagos

**NOW, AVAILABLE**

BUGLES, BEDSTEADS PAINTS DISTEMPERS, SAFES Etc.
Just write, Call, or Phone 21372

**IKORODU TRADING COMPANY**

20/28, Balogun Street, (P. O. Box 395) Lagos,
AND
NEW COURT ROAD IBADAN

**HINDU SANKARA'S**
**Religious Art Jewelleries**



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, Kawachas, Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

*Enclose (?) money order by Air Mail for Catalogue and Literature.*

HINDU SANKARA, 12 Scarborough Gardens Westminster, London, S.W.1. England

# Mana-mana Pa Qmo Ilewe Meta

**Onitsha** Agbo irohin wipe aiun ilewekan ti a npe ni Okongwu Memorial Grammar School ti o wa ni ilu Onitsha, ibe ni mana-mana se jamba fun awonyakoko inu ilewe na,

Laseko ti awon mbe lenu ise ni mana-mana na da yeri t i o s i p a awon enia meji yi leso Keneth ati Maikel.

George Otereke, ati Kristian, Akor ni awon ti o pa patapata, eniketa ti mama-mana na ton pa ni Daniel Ojiuo, eniti o nka iwe lowo nigbati Asaraila yo si lojiji,

Kowo iku ojiji oluwa rere gba wa

# Tani Le Tumo Qro Yi

Olotu

Bi enia ba nke ogbọn, o yọ ki ọgbọn na tunbọ ma ga siwaju. Mo ti ṣakiyesi wipe ogbọn ati imọ awọn ọkawe ti ga nisisiyi li o ṣe jẹki nmu idanrawo yi sode.

A nfẹ ẹniti yio tumọ ọrọ yi lati oke dele fun idaraya, Ọrọ na niwọnyi:-

A. T. gba W. pe, I. ru tẹ ṣowọn G. D. G. D., B. O. T. lejẹ arẹwa obinrin, Ko le rẹwa K. A. F. we Ayaba Kleopatra.

Sugbon lalẹ ele lẹẹ, oju rẹ mọlẹ B. oṣupa ọjọ mẹrindilogun T. O. Y. R. B. T. ohun rẹ si dun L. orin kiko.

B. ọmọ ẹni ba dara, o yẹ K. A. W. L. O. T. tọ A, T. L. ododo, ẹwa rẹ pọ G. D. G. D. Koi T. S. ẹlẹgbẹ rẹ.

Emi ni
Alufa Imam Adoon

# Idahun Si Ibere Williams.

OLOTU,

Gba mi laye lati fesi si ibere Ogbẹni B. O. Williams. Meji pere ni ngo dahun ninu ibere, ṣugbọn ẹkẹta ninu ibere na ni ngo dahun niba jaba.

Idahun Kini, Ọlọrun sọ wipe k i gbogbo enia lọkunrin ati li obinrin m a sin On ṣugbọn Anobi sọ wipe:-

Idahun Keji. Ọkunrin ati Obinrin ko gbọdọ ropọ nino Safu kanna lati sin Ọlọrun, bi ko se wipe ki obinrin to Safu tire lọtọ ki ọkunrin si to tire lọtọ,

Idi re ti o fi wibe ni wipe bi ọkunrin pelu ob'nrin ba to Safu kanna bi nwọn ba nfi ara kan ara ọkan awọn mejeji ko ni si nibi esin, eyi nidi ti obinrin ko fi mba ọkunrin ṣe isin papọ.

Ẹketa ti ngo dahun jaba ni wipe Ọlọrun sọ bayi ninu Alukurani pe On ko nse Ọlọrun Oku bi ko se Ọlọrun Alaye Bibeli sisọ wipe awọn oku ti o ti ku ko le yin Ọlọrun mọ bi ko se alaye.

Eyi nidi re ti imale ko fi ngbe oku wọn wọ inu Mọṣalasi.

Emi ni
Malam R.A. Ayinla,

**Ọse Palmolive Le Jeki Ara Re Ro, Ki o Se Fulofulo Larin Ọjo Merinla**




**Ewa jade lara mi nitoripe motele ilana ti Dokita se**




Iba nkan ti iwo yio se niyi
1 Fi ose Palmolive we oju
2 Fi hiho re pa oju fun iseju kan.
3 Fi aso nu kuro se be nigba meta lojumo fun ojo merinla.

Epo Ile Afrika ni a fi se

## Gehin-gehin

Dan egbogi yi wo fun u. ti o ba di wipe ehin ndu enia de ipo ti ko le bere, Kindirin lo fa a Nitoripe ise Kindirin ni lati se idoti kuro ninu eje ara enia, nigbamiran ewe ko ni sise deedee, Ehin ti o dun ni je ikilo fun enia wipe Kidirin ra ko sise to, o si nfe iranlowo egbogi De Witts ni a kiro pe o le je awosan na Nitoripe egbogi na ko ee iru ise be ri ri. Dan wo, lo ra ekan wo ni sobu.



Ohun to da wa loju ni wipe Egbogi DE WITT,S PILLS je eyiti a se tonitoni ohun elo re gbogbo lo si me

DE WITT'S PILLS
for Kidney and Bladder Troubles

## Nje Jesu Ha Mu Oti Ri

Oloto,
Ohun ti emi le so, ti nwon npe ni Oti ni Oti Jini, Oti Sitapu, Oti Dry Jini, Oti Wiski, ati Oti Red Label,
Eyiti mo mo ti nwon npe ni Walei ni Emu Burukutu, Vito, Sekete Halls Waini.
Ofin Mose so wipe iwo ko gbodo mu oti lile Solomon si so wipe fi oti lile fun eniti o fe fi opin si emi re
Ibere mi ni wipe, "Nje Jesu ha mu oti ri ndan?

Alhadji Karaole

## Egbe Omo Oduduwa Se Idagbere Ni Otta

**Otta** Ko si botiri ni ipade egbe omo Oduduwa ti awon se nilu Otta oba Olota lo se Alaga, awon ijoye re rogba yi ka,

Ogbeni Isaac Delano ti o nse Sekiteri egbe yi so wipe Iran Yoruba se oriire tobe ge ti o fi je wipe ile wa li o nsan fun wara ati fun oyin, Ohun pataki ti a da egbe yi sile fun ni wipe ki gbogbo iran Yoruba le ekan,

Ojikutu-joye oba Olota ti o nse Alaga so wipe bi enia ba gun esin nlen on nisisiyi gere ni yio lo fun ti egbe Oduduwa ti nwon da sile ni ilu on yi.

Alhadji A, T. Ahmed ti o nse asoju fun ilu Otta ninu igbimo House of Assembly dide dure o si dupe lowo awon ere ti o wa ati lowo Delano ati lowo awon ijoye ati awon omo oba. Opolope awon omo ilu Otta ti o ngbe Eko, Yaba, Idi-Oro ati Agege lo wa si ipade na,

## ARA OKE OKUN WA BE ELETI OFE WO

**Eko** Gbuke ni a ri awon alejo wa meji ti awon nse ara awon okowo wa li oke Okun ti o bo oko M.V. Accra gunle si Eko ti awon si wa bo wa wo.

Awon alejo wa mejeji na ni Ogbeni Paul D. Osirele ti o nse Alaga omo Ogbomoso Parapo li oke Okun Britanna ti o si tun je Olotowo patak, Ekeji ni Ogbeni Joseph Oyedeji Onisowo

Awon enia mejeji nwonyi je enia pataki larin awon omo Ogbomoso nwon ti ba ise owo sise lo si okun sugbon nisisiyi nwon nlo si ilu Ogbomoso lati dasa lo wo awon enia won, A fi eyi ki Councillor Ara-ogbe ku afojuba.




ILE EKQ GIGA UNIVERS TY COLLEGE IBADAN

Awon omo ile Eko University ni Ibadan a ma se iranti nigba gbogbo iru ilosiwaju ti a ti se nfie enia dudu, nitoripe awon ile nlanla ti nwon nsise ninu re je apakan ninu re je apakan ninu ilosiwaju na. Simenti oyinbo Burham ti Portland se die ninu iranlowo yi, nipa wipe on ni a fi ko awon lie na, ati opo awon ile nlanla miran kakiri agbegbe ibe. Niwon adorin odun sehin ni oyinbo Burham ti nse iranlowo fun idagba soke ile enia dudu. O si ti fihan wipe, Simenti ti on li o lagbara ju on li o si dara ju o ni gbogbo agbaiye.

BURHAM
PORTLAND CEMENT

**Mo Gbadun Siga Pirate**




# PIRATE

**Je Siga To Dara**


## Survey Department, Western Region. Vacancies For Surveyors.

Applications are invited from suitably qualified candidates for the filling of vacant posts of Surveyors in the Survey Department in the Western Region of Nigeria.

Scale of Salary :— A. 1. i.e. £570 - 40 - 1,290 per annum.

Qualifications :— The posts are open to men only who should be over 21 and not normally more than 40 years of age though due consideration will be given to suitable candidates a few years over this age, applicants should possess one of the following qualifications —

EITHER (i) (a) A University Degree in Physics, Matehmatics or Geography PLUS

(b) The Intermediate Examination of the Royal Institution of Chartered Surveyors in the Land Surveying Section (or exemption therefrom),

OR (ii) Full Corporate Membership of the Royal Institution of Chartered Surveyors, i.e. the qualification of Professional Associate (A.R.I.C.S.) in the Land Surveying Section.

OR (iii) In the absence of candidates with either of the above two qualifications, consideration will be given to applicants who have not less than 15 years satisfactory service as a Junior Service Surveyor in the Nigerian Survey Department and who have had experience in all branches of field survey work,

Duties :- Officers appointed may be required to take charge of Provincial Survey Offices, including field and office staff, or to supervice a party of Survey Assistants in the field, or to undertake field survey work of such a nature that it cannot be entrusted to Junior staff.

Applications should be addressed to the Secretary, Public Service Commission, Western Region, Ibadan, so as to reach him not later than May 5th 1955.

(i) Applications from candidates not in Government Service should be completed in duplicate on the prescribed form which may be obtained from all Residents in Provinces, and from the Nigerian Information Service in Lagos, Ibadan, Kaduna and Enugu

(ii) Applications from candidates in Government Service should be submitted through the Head of the applicant's Department and be accompanied by a confindential report on the new Confidential Report form.


## STOCKFISH

Order the best packed Stockfish through MESSRS WARDLE & CAPELL, BRAUNSTON RUGBY ENGLAND. Orders are accepted on their behalf by THE EBUN-OLU STORES of 38, Kosoko Street, Box 771, Lagos.

Deposit required 15o/o balance payable through Bank on arrival of goods.


WESTERN REGIONAL PRODUCTION DEVELOPMENT BOARD

WRPDB

## PIONEER OIL MILLS

The Western Regional Production Development Board is willing to hire out to private individuals or communities a limited number of Pioneer oil Mills in the Western area of the Region. These mills fall into two categories.

(a) Those erected and ready to go into production

(b) Those delivered to site and/or partially erected and which will be erected by W.R.P.D.B.

There is one mill of the first category in each of the following places: Mosan, Akolu, (Abeokuta Province), Odo — Oba, Araromi (Ibadan Province) Ago Iwoye (Ijebu Province) and Irele (Ondo Province)! and one mill of the second category in each of the following places: Oke Ate (Ijebu Province) Aradagun and Nuka (Badagry Division).

2. The annual rent chargeable per mill would be £200 per annum and the Board would provide maintenance and other services for a norminal charge.

3. Moreover, during the period ending 31st March, 1956, the Board would be prepared to help prospective tenants thus:

(a) To grant loans to cover cost of Transport and working capital on production of two guarantors,

(b) To charge only half-rental,

(c) To provide maintenance and other services at a reduced charge of 50 o/o.

4. The tenants will be given the opportunity of buying the mills at advantageous terms if they so desire.

5. For further particulars, Please apply to the Secretary, Western Regional Production Development Board, I b a d a n, Applications received after 30th April will not be considered.


# REDIFFUSION

THE BOX THAT TALKS SINGS & BRINGS MUSIC TO YOUR HOME

Costs less than 3d a day and gives you pleasure for 17 hours.

MAINTAINANCE FREE! ARE YOU A SUBSCRIBER?


...ing and Publishing Company, 28 Kosoko Street P. O. Box 467 Lagos, Phone 23370